Ede Yoruba یـوربا

# Zakat ipin meji ni

**1. Zakat naafila:** Oun ni gbogbo owo ti eniyan ná lati le fi ṣe ijọsin pọnnbele fun Ọlọhun.

**2. Zakat ọranyan:** (O pin sí ìran meji)

## zakat ara :

Oun ni a npe ni Zakat ul Fitir, ó jẹ ọranyan fun gbogbo Musulumi, agba tabi ọmọde, ọkunrin tabi obinrin, ẹru tabi ọmọlabi.

## Zakat owo:

Itumọ rẹ ninu sharia ni pe: (jijọsin fun Ọlọrun Ọba pẹlu yiyọ ipin ọranyan ti sharia jade ninu owo fun awọn kan pato) Zakat ni òpó kẹta ninu awọn òpó ẹsin Islam,

ó sì pín sí ipin mẹrin:

**1 Awọn owo meji**



awọn naa ni wura ati fadaka ati awọn nkan ti ó le rọpo wọn ninu awọn owo pépà ati owo miiran. Odiwọn ti zaka wọ̀ ninu wura jẹ 20 mithqal (85 gram), odiwọn ti zaka wọ̀ ninu fadaka jẹ 200 dirham (595 gram).

**2 Awọn ẹran ọsin**



Eyi tí ó ńjẹ koriko ẹ̀tọ́ káa kiri fun nkan tó sunmọ ọdun kan tabi ọdun kan gbako, ati pe nkan ti a gba lero pẹlu awọn ẹran ọsin ni: Rakunmi, malu, ati agutan.

**3 Awọn nkan tin jade lati inu ilẹ**



awọn naa ni awọn irugbin ati awọn eso

**4 Awọn nkan iṣowo**



Awọn naa ni gbogbo nkan ti a gbe kalẹ fun tita ati rira

## Awọn tí a ó fun ni zakat :

**1 Awọn alaini:** awọn ni awọn ẹni tí wọn kò ní owo kankan ti wọ́n ó fi gbọ bukaata tabi kí wọ́n ní diẹ tí kò lè tó wọn.

**2 Awọn talaka:** awọn ni wọ́n ní pupọ tabi aabọ ninu nkan tí yoo to wọn, Lapejuwe kani 12,000 ni yoo to onitọhun fun ọdun kan, Alaini yoo ni ẹgbẹrun mẹfa tabi kí ó má ni nkankan. Talaka ni ẹni tí ó ní ẹgbẹrun mẹfa tabi ju bẹẹ lọ ṣugbọn kò tó 12,000, nitori pe a nfun talaka ati alaini ní ohun ti yoo to awọn mejeeji fun ọdun kan, ati pe zakat jẹ ọranyan ni ẹẹkan ni ọdun.

**3 Awọn ti wọ́n n ṣiṣẹ lori zakat:** Àwọn ni wọ́n gba zakat jọ, ti wọ́n tọju rẹ, ti wọ́n sì n pin-in, Olori ilu ni ó fà wọn kalẹ, kò sì kíí ṣe dandan ni ki wọ́n jẹ alani ki a tó lè fun wọn ninu zakat, a n lati fun wọn ninu zakat koda ki wọn jẹ́ ọlọrọ

**4 Awọn ti a fẹ fa ọkàn wọn mọra:** ninu awọn ti a fẹ ki wọn gba ẹsin Islam, tabi ti a fẹ dènà aburu wọn, tabi ti a fẹ jẹ ki igbagbọ wọn lagbara si

**5 Lati fi tú okun ẹru kuro ni ọrun awọn wọnyii:**
A – Musulumi tí ó jẹ́ ẹrú afiwe kọ
B - Itusilẹ Musulumi tí ó jẹ́ ẹrú
C – Musulumi tí ó wà ninu ìgbèkùn

**6 Awọn oni gbese:** awọn ni:
A- oni gbese nitori a ti ṣe atunṣe laarin awọn eniyan
B- oni gbese nitori ara rẹ

**7 Lati na a si oju ọna Ọlọhun:** Ninu rẹ ni nína zakat fun awọn olujagun ẹsin ati lati fi ra awọn ohun ti wọ́n nii lo bi nkan ija ati awọn nkan miiran

**8 Ọmọ oju ọna:** Òun ni arìnrìn àjò ti n kọja lọ, tí owo rẹ̀ sì ti tán, nitori naa a ó fún un ní owo tí yóò gbé de ilu rẹ̀

sarhaan.com
mahadsunnah.com